igbagbo re mu o larada. Olorun fi ife n la re han si okunrin afoju yi pelu ijewo igbagbo re ninu Jesu Kristi o si mu larada. Niwon igba ti Olorun le fi ife nla Re han okunrin afoju alagbe yi, o setan lati fi ife nla Re ba iwo naa gbe po.

**Luku 18:42 Jesu si wi fun pe, Riran: igbagbo re gba o la.**

**Iye Ayeraye**

Bibeli je ki o ye wa pe Olorun feran araye, sugbon iye awon ti o ba jewo Jesu gege bi Oluwa ati Olugbala ni yo wo ijoba orun. Ninu iwe Ifihan, nibe ni ati ri idi ti awon eniyan fi wa ni orun. Awon ti o gbagbo pe Jesu ku ti o si ta eje re sile nitori ti won awon eniyan won yi wa lati onirunru eya, ede ati gbogbo agbaye, Nitori Olorun fe gbogbo eniyan ni gbogbo aye.

**IFIHAN 5.9 Won si n ko orin titun kan, wipe Iwo ni oye lati gba iwe naa, ati lati si edidi re, nitori ti a ti pa o, iwo si ti fi eje re se irapada eniyan, si Olorun lati inu eya gbogbo, ati ede gbogbo, ati inu eniyan gbogbo, ati orile ede gbogbo wa.**

Fi aye gba okan re lati gba adura yi, ki si gba ife Olorun ninu okan re fun idani loju ayeraye pelu Olorun.

Olorun mo jewo ese mi mosi setan lati gba Jesu. Mo gbagbo pe ninu ife Re si aye ni o se ran Jesu lati ku lori agbelebu, ti o si ta eje re sile lati san gbese ese mi. Mo gbagbo pe oji dide ninu oku. Bayi mo gba Jesu gege bi Oluwa ati Olugbala mi. Jesu ni Olugbala mi. Mo di ajogun ijoba ayeraye, ohun si ni Abba Baba fun mi. Ose ni oruko Jesu. Amin.

Baba iwo ni o ran Jesu lati se iwosan okan onirobinuje, wo okan irobinuje eniti o n ka iwe yi san, boya isoro kan, tabi aisan, eyikeyi ohun ti owu ki oje. Jeki owo iwosan Re ki o se iwosan itusile ki osi wa. Gbogbo owo anini lara, ati eyi ti esu n pon loju, okan ti o fe pokini so, tabi ogun oloro mimu ki won gba itusile, labe ife n la Olorun. Ki gbogbo eniyan si wa labe ife, ayo ati alafia Re. Amin.

**Romu 8: 32 Em ti ko da Omo oun funra re si, Sugbon ti ojowo re lowo fun gbogbo wa, yoo ha ti se ti ki yoo fun wa ni ohun gbogbo pelu re lofee.**


**CHAPLAIN JOHN McTERNAN**

**PASTOR OYEWALE S. A.**
***(OGO-OLUWA)***
*Abba Father's International Fellowship*
*P. O. Box 120,*
*Ede, Osun State, Nigeria*
*TEL: 08035375916*


# JOHANU 3:16

Nitori Olorun fe araye tobee ge ti ofi omo bibi Re kan soso fun ni,



ki enikeni ti o ba gba a gbo maba segbe, sugbon ki ole ni iye ainipekun
Johanu 3:16

NITORI OLORUN FE ARAYE

Bi o se nka iwe yi, Bibeli je ko ye o pe Olorun feran re. Eyi ko ni se pelu ojo ori re, boya okunrin ni o tabi obinrin, olowo tabi talaka, ipo ti odimu, ibi ti o ngbe tabi ibiti oti jade wa. Olorun ni oun feran re. Eyi je oun iyalenu nla pe eniti oda aye ati orun feran re. Pelu gbogbo agbara ti Olorun ni, Bibeli je ko ye gbogbo iran eniyan pe Olorun je ife. Nitori pe Olorun je ife, ofe lati ni ajosepo ife pelu re.

**I JOHANU 4:8 Eniti ko ba ni ife, ko mo Olorun, nitori pe ife ni Olorun.**

Olorun dawa ni aworan ara Re pelu ife, ki oba le fun wa ni ife Re pipe ati ki ale gba ife Re. Olorun to pese aye nla kan sinu ago ara wa ti ife Re le maa gbe.

Awon nkan meta kan se pataki fun eniyan lati wa laaye. Afefe, omi ati onje. Ti ko ba si afefe eniyan kole wa laaye, bee na ni eyan kole wa laaye ti ko ba mu omi fun awon ojo die tabi je onje fun osu kan. Iru enibee ko le wa laaye. Eyi je afiwe eniti oba fe gbe igbe aye onigbagbo tooto. Ogbodo ni ife, gege bi Olorun se ni ife gbogbo eniyan. Ife, igbagbo ati ireti se pataki. Awon ti ko ni ife maa nje akorira, onija, alailaanu, apaniyan, jagidijagan ati beebee lo. Iru awon eniyan bee ti di oku nigba ti won won wa laaye.

Sugbon awon ti ife Olorun kun okan won maa ni suuru, ayo, anu, ipamoran ni igba gbogbo. Iru ife wo ni Olorun nfe lati odo awa eniyan?

Olorun nfe ife eyi ti Baba maa ni si omo re kekere, eyi ti omo fe ma pe Baba tabi "Abba ni Ede "Heburin" Eyi ni ife ti o jinle ti osi ni agbara ti be ti Abba-Baba kii le fi omo Re sile tabi gbagbe omo Re.

**Romu 8:15 Nitori eyin ko tun gba emi eru lati má beru mo. Sugbon eyin ti gba emi isodomo nipa eyi ti awa fi nke pe ABBA, BABA**

Ona wo ni ogba da o loju pe Olorun feran re. Odun lati soro, opolopo awon oniro si po ninu aye. Oro ti aso ti ko ni atele iwa gege bi otiso. Agbodo soro ki iwa ati ise wa si jeri oro ti aba so. Iwa eniyan ni omaa nfi oun ti eniyan je han.

Ohun gbogbo ti Olorun ba so ni o maa mu wa si imuse. Ko si eri ti oju eyi lo pe Olorun ran omo bibi Re kan soso Jesu Kristi lati ku fun ese araye. 1 Johanu 4:9 Nipa eyi ni agbe fi ife Olorun han ninu wa, nitori ti Olorun ran omo bibi Re nikan soso si aye, ki awa ki ole ye nipase Re.

OLORUN FI OMO BIBI RE KAN SOSO FUN NI

**Romu 5:8 Sugbon Olorun fi ife oun paapaa siwa han ni eyi pe, nigba ti awa je elese, Kristi ku fun wa.**

Idi pataki ti Olorun fi ran omo Re kan soso si aye ni lati ku ni ori igi agbelebu ati ta eje re sile ni lati san gbese ese araye. Olorun je mimo laije mimo eniyan ko le de ijoba orun pelu Olorun Jesu san gbese ese araye ki aba le wo ijoba orun. Olorun je mimo, idi niyi ti ose san gbese ese wa nipase Jesu Kristi lori igi abgelebu. Eyi ni o fun wa ni ore ofe lati di ajogun ijoba Olorun pelu ABBA BABA.

**Rome 6:23 Nitori iku ni ere ese sugbon ebun ofe Olorun ni iye ti ki nipekun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa.**

Enikeni ti oba gbaagbo ma ba segbe, Sugbon ki ole ni iye ainipekun.

Ari apere ninu Bibeli ti ofi han wa pe enikeni ti oba pe oruko Jesu Kristi ni a o gbala, ti yo si ni iye ayeraye. Arika ninu Bibeli nipa, afoju kan ti a npe ni Bartimeu o joko leba ona lati maa sagbe, ko ni ise tabi ibugbe ohun ti awon ti won nkoja ba fun ni ogbekele lati je ati mu. O gbo ti iro opo eniyan n koja lo o si wipe ki li eyi won si wifun pe Jesu ti Nasareti ni o n koja. O si kigbe pe Jesu iwo omo Dafidi saanu fun mi. Awon eniyan si gbiyanju lati paa lenu mo. Sugbon otun kigbe sii kikankikan. O wipe Jesu omo Dafidi saanu fun mi. Ni igba yi ni Jesu duro o pase ki a mu Bartimeu afoju naa wa. Jesu si wi fun pe kini iwo nfe o si wi fun Jesu pe, ki emi ki oriran. Jesu da lohun pe riran,